**Akiyesi**

A nfẹ awọn enia ti yio ma ba wa ta Irohin Imole ni awọn ilu wonyi Igbo-Ora Shaki Iseyin Erowa Lalupọ Akure Ondo Ado-Ekiti Gbogan Fiditi Oyo Ede Ikorodu Shagamu Ilaro ati Ilora.

Ẹ kowe si:-
Olotu IROHIN IMOLE
16, Bamgbose Street,
Lagos

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Lakaye oro**

Irọ ni Babalawo npa ko ri Ifa
Irọ ni Omisegun npa ko ri ogun.

Awọn abo Egungun ki ri Egungun.
Aborisa ko ri orisa
Olorugbo ko jẹwọ atanmije bi olorun.
Eke tan ni sija Ẹkun

VOL. VI No. 330 MONDAY MAY 21 — MAY 27 1962 KỌBỌ MEJI (2)

# Ara Ibẹfun kan gbe Ori Enia pamọ si abẹ ibusun rẹ, Ọlọpa ri, o di ẹjọ

Ibefun:- Lojiji ni awon Olopa ro giri-giri wolu Ibefun lati Ilu Ijebu - Ode nibiti nwon gbe nwa ohun kan, ni nwon lo kan igba ademu nla kan ti nwon ta epo si ni abe Ibusun.

Gẹgẹbi oju awọn Ọlọpa ti ri Ṣango ode ri, nitorina, nwọn fẹ lati ri Ọya inu igba na. Ṣiṣi ti awọn Ọlọpa ṣi igba na, ori enia ni nwọn ri, ti wọn si we ni aṣọ funfun, ori na jẹ tutu.

Eniti o wa ṣe ofofo ọrọ yi fun awọn Ọlọpa ni awọn Ọlọpa tun ramu pẹlu awọn ti o haya ile na ati ẹniti o ni bẹdi ti nwọn ba igba yi ni bẹ sẹ.

Larapa ori tutu yi, awọn Ọlọpa mu Ọkunrin kan ti o njẹ Jimọ Adekoya, nibiti awọn Ọlọpa gbe nṣe iwadi nwọn ri Idi waya, eyiti awọn Ọlọpa ro wipe boya nwọn ji lọwọ Post & Telegraph ninu ile ẹniti o wa ṣe ofofo.

Awọn Ọlọpa mu Ọmọkunrin kan ti o njẹ Moṣudi, ṣugbọn nwọn fi silẹ laipẹ. Ẹjọ bi ori tutu na ti ṣe rin ki o to de abẹ bẹdi si mbẹ nikawọ awọn Ọlọpa, bi a ba si ti tun ngbọ si, ẹ o ma gbọ.

## Aṣe ilu miran wa nilẹ Naijiria ti Ijọba ko tilẹ mọ pe nwọn mbẹ ni bẹ

KALABA:— Ọpọ awọn enia lọ ti nkigbe wipe owo ti Ijọba da si Ilu ko to awọn enia lati na, bi nwọn ti nko owo na wọlu bẹni o nṣe ṣiọra, ṣugbọn akara tu sepo nigbati awọn ti o nka enia de ilẹ Kalaba, ibẹ ni won gbe ti lọ ri awọn ẹya Ijọ kan ti wọn ngbe eti odo ni Oka. Leti odo kan ti wọn npe ni Alapa ni apa iṣalẹ Ilu kan ti nwọn npe ni Uruan lagbegbe Uyo nilẹ Kalaba.

Awọn ti o ngbe Ilẹ na jẹ orisirisi ẹya enia ti wọn si nsọ ede miran ti o yatọ patapata si ede Kalaba, Ninu wọn, ẹya Ijọ ti o ngbe eti omi wa, Efiki wa ninu wọn bẹni awọn Ibibio wa ninu wọn. Apapọ awọn enia wọnyi ni iṣiro to ẹgbẹrun enia ti enikan ko si tilẹ mọ pe iru awọn enia bawọnni mbẹ ni bẹ.

Bakanna ni awọn ti o nka enia tun ri awọn ẹya kan to ẹ wipe Iṣẹ apọja ni wọn nṣe ti Ijọba ko si mọ pe, iye awọn enia to pọ to iwọn Ọkẹ kan enia mbẹ ni gbẹgbẹlẹ eti odo ni Ilu Ẹkẹt.

A gbọ pe awọn ẹlẹwọn to mbẹ ni Uyo taku wipe, ẹnikan ko gbọdọ kọ oruko wọn silẹ. Edekoyede to mbẹ larin ẹbi Anyanya ti wọn taku pe awọn ko ni fi oruko silẹ ti pari, gbogbo wọn si ti foruko silẹ.

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ndabira

Lọjọ Isinmi (Sunday) ti o koja lọ yi, ni awọn ọmọ Ẹgbẹ New Nigeria ba ọmọ Ẹgbẹ Little Torrist ta pero ere bọlu ẹlẹsẹ. Ṣugbọn ọmọ ẹgbẹ New Nigeria lo bori ere na. Awọn pataki ibẹ ni Saubana Balogun, Charles Apena ati Albert John.

ADVERTISEMENT NO. 76.

**KERE O**

OFIN TI A NFI NA OWO ATIJO (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS) DI PI PARE

A fẹ lati ran gbogbo enyin enia leti wipe ati ọjọ kini oṣu July, 1962 (oṣu keje ọdun yi) gbogbo owo Atijọ patapata eyi ni owo Pepa ati owo Ṣile titi de ori Epini yio kuro. A ko ni le lo wọn gẹgẹ bi Ofin ni ilẹ Naijiria.

Eyi ni wipe lati ọjọ kini oṣu keje (July) ọdun yi, owo Atijọ wọnyi koni wulo fun sisan owo fun Iṣẹ Aje ni jake jado ilẹ Naijiria - fun apejuwe, aikoni gba fun Ọja rira tabi fun Ọja tita ninu Ọja ati Ṣọbu.

Gbogbo ẹniti o ba ni owo Atijọ wọnyi lọwọ tabi ni ipamọ yala ni pepa tabi ni Ṣile ni lati tara lọ ṣe paṣi parọ owo wọnyi ni Bank ki Bank fun owo titun eyiti Central Bank ti Naijiria fi sita ni nkan bi ọdun kẹta sẹhin ti a si na lọwọlọwọ yi ki ọjọ kini oṣu keje ọdun yi (July) to to. Ọfẹ ni gbogbo Bank yio parọ owo wọnyi fun yin.

JOHN BEACH
Deputy General Manager.

Central Bank of Nigeria,
Lagos.

# Ọrọ Olotu

## Adan dori kodo. o Nwoṣe Ẹiyẹ

Ija lo de lorin di o w e, ṣugbọn bi a ba nsọkun a ma nriran. Gbogbo wa ni a fẹ ki ija pari, ki itukerudo dopin ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre. Ṣugbọn lati igbati rogbodiyan ti bẹ silẹ ti a ti ngbọ orisirisi ọrọ lati ọnu ọtun ati osi eyiti o nipọn ju ni ibere ti Oloye Enahoro bere pe "ṣe ẹgbẹ ni o yẹ ki o ma gba'ṣẹ lọwọ ijọba ti o yan ni tabi ijọba ti ẹgbẹ mu wa saiye ni ki o ma gbaṣẹ lọwọ Ẹgbẹ?"

Ibikibi ti awọn onilaja ba pari Ija y si laidahun ibere wọnyi, nwọn ge Igi Paki nwọn tun rin mọlẹ ni. Bo pẹ r hu ni ọt un

O yẹ ki o ye ẹnikẹni n o ba ninu igbimọ pe ẹgbẹ ni o polowo Ibo fun on oruko ẹgbẹ ni on fi wọle, agbara ẹgbẹ ni on fi njoko sile igbimọ, ẹgbẹ si ni agbara lati fa on sẹhin.

Awa nwo iṣe yin, Ṣugbọn ki ẹ mọ pe ibikibi ti Ija yi ba ja si ṣe pataki fun ọh n ọla.

## Ọjọgbọn Akẹkọ Ẹgbogi ọmọ ilẹ Naijiria



Aworan ẹniti ẹ nwo yi ni ti O m i d a n F. Odutọla ti Ijẹbu ode, o ndan awọn egbogi kan wo, pẹlu Olukọ rẹ Dọkita L. Elison ni Woolwich Polytechnic nitosi London.

Omidan Odutọla nkẹkọ iṣẹ Dọkita ni ile ẹkọ yi yio si ṣe ọdun meji nibẹ, Lẹhin ọdun meji yi ni Omidan F. Odutọla yio wa lọ si Ile iwosan, ninu awọn ile iwosan ni ilu Gẹsi lati tun kọ akọyo ẹkọ rẹ nipa egbogi ati wosan

# Yẹyẹnatu!

## O NI NẸYẸ EKO

Yẹyẹnatu:— Ha! ori Suberu ma pe o.
Olotu:— Ṣe o pe to ti Alajo?
Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹ mọ pe ọmọ Lemọmu lo fẹ?
Olotu:— Hẹn o! Ha, iyẹn ni ko pa ẹran Ileya?
Yẹyẹnatu:— Ko pẹran, ṣugbọn o ha ẹran.
Olotu:— Ko ha fun emi ṣa
Yẹyẹnatu:— Ko ha emi na, Lemọmu nikan lo ha
Olotu:— Ṣe bi o ni ko pẹran, nibo lo ti ri ẹran ha?
Yẹyẹnatu:— A ni ori Suberu pe. Nigbati Iyawo rẹ gba ẹran de lati Ile wọn, o j a d e lọ, ki o to de Suberu ge diẹ ninu ẹran na, o fi pamọ, o sare fi nla ti o kuṣranṣẹ si Baba Iyawo rẹ, o ni ẹran ọdun ni yẹn.



Olotu:— Ha! ha! Ori Suberu pe loto, lo ba fi ẹran ranṣẹ pada sibi to ti wa.
Yẹyẹnatu:— Igbati Lemọmu ti sọ pe ko gbọdọ ma pẹran
Olotu:— Ṣe Iyawo re ko b e r e ẹran mọ ni, nigbati o pada
Yẹyẹnatu:— Ha! ẹ ko mọ o h u n ti Suberu ṣe ni?
Olotu:— O ko yi sọ fun mi kẹ
Yẹyẹnatu:— Lotọ ni ṣa, Yẹs kẹ
Olotu:— Ki lo ti ṣe?
Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹ ri ẹran kekere to ge pamọ yẹn, nigbati o gbọ iro Iyawo rẹ o gbe fun aja wọn. Bi Iyawo ti wọle, o ri ja nibiti o ti njẹ ẹ r a n. O kigbe, lawọn mejeji ba nlaja kiri
Olotu:— Ha! ha! ha! Iyawo ro pe aja ti gbẹran
Yẹyẹnatu:— Hẹn o! Ni Suberu nsare jilajila le a j a, ti Iyawo rẹ nṣe pe lo nbu aja. O ni Olo riburuku, ole.
Olotu:— He, o maṣe o.
Yẹyẹnatu:— O tun doju kọ ọkọ rẹ o ni on lo jẹ ki aja gbe ẹran on. O ni ko le pẹran, o tun jẹki Aja gbe eyiti nwọn fun on. Ibiti o ti nbu Suberu, ọmọ ti Suberu ran si Lemọmu de o ni "nwọn ni ọbẹ ko ni sele o".
Olotu:— Ha-ha-ha. Ori Suberu ti pe, Ṣe ẹnyin obinrin kan ngbọ gbawu ni ẹ ko mọ ibiti Ibọn ti ndun.
Nwọn ni Kontri hadi
Yẹyẹnatu:— Manu hinono
Olotu:— Wumanu hinono ni nwọn nwi
Yẹyẹnatu:— Ẹjọ nyin.

## Awọn Serafu tako ere Ẹlẹṣẹ pe ko dara

P. Harcourt:- Ninu ajọdun kẹwa ti awọn ẹgbẹ Serafu ṣe ni ilu Port harcourt nwọn fi imọ ṣọkan lori ere ẹṣẹ jija wipe, ere yi ti ko ni ere alafia ati Idẹra, o ti di ere yohinyohin, ẹniti o ba si jafara ninu awọn elere ẹṣẹ meje ji, eleyini nlọ si ọrun alakeji nuni.

Nitorina awọn ri wipe ere ẹlẹṣẹ ko si ninu awọn ere to dara fun ọmọluwabi. Nwọn ṣakiyesi pe ọpọ awọn ọdọ ti iba wulo lẹhinwa ọla ni ere ẹṣẹ ti ran lọ si aiyeraiye.

Nwọn kọwe si Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa ti iṣẹ olori Ijọba apapọ pe ki o mu ere ẹṣẹ jija kuro ninu eyiti a le fi ṣe ọmọkunrin.

Bi a ba ti tun gbọ ọrọ na si, ẹ o ma gbọ.

## Okotie Eboh fun Ọba Gẹsi ni Ẹbun

London: Ninu irin ajo oloye Okotiẹ Eboh tiṣe alaṣẹ eto owo ilẹ Naijiria silu Gẹsi ni a gbọ pe o ya ni afin Buckingham Palace lati lọ bẹ ọba Elizabeth keji wo, nigbati o si de ọdọ ọba Gẹsi na, o gba ọwọ tẹṣẹ.

Oloye Okotiẹ Eboh si fun Ọba obinrin na ni ẹbun buroṣi ohun ti wọn fi nṣe oṣọ igba aiya ti a fi Gold Naijiria ṣe.

# IFẸ LOJU (APA KEJE)

Nigbati ara Muli si ti ya dada lati ma lọ ṣiṣẹ owo rẹ Iya rẹ ni ko gbọdọ lọ kiri. O yẹ ki O j o g ẹ si ile Itaja nla kan fun, o pe O j o g ẹ, o sọ ọrọ na loju rẹ, Ojogẹ si dahun pe anu ṣe on pe on ko ni owo lọwọ ti on le fi ṣe iru nkan bẹ ni igbayẹn. O si leri pe on yio fi si ọkan lati ṣe, ṣugbọn inu on yio si tun dun bi Iyawo on ba le ma gba Ọja ti o si nta won bi o ṣe ma nṣe ki o to bimọ

O ni Iya, nko tilẹ fi ṣọ asọdun, ni ọjọ kan, Iya Bọlaji a ma jẹ bi pọun mẹjọ tabi mẹsan lere, ọwọ rẹ ji si kini na gan, Inu emi p a p a si ma ndun si, ṣugbọn nigbati Iya Bọlaji bimọ tan ni iwa rẹ ti yatọ pupọ si mi. Ju gbogbo rẹ lọ ni ti ọrọ ti ẹ ba mi sọ yi, Iyawo mi mọ ile ati ọna mi, o mọ iwọle ati ijade mi ki o to ma sọ wipe on ko ni ṣe ohunkohun mọ afi ti mba da on loko owo, ki nsi ṣi ile Itaja nla fun on, Iya Muli si dahun o ni "Hẹn" ko purọ, Iwọ na ko mọ pe abuku ni o jẹ fun Muli lati ma du kiri, lati ile Itaja oyinbo kan bọ si ekeji ati lati ma gbe kiri fun Onibara. O gbagbe pe ọmọ ori Ọla ni Muli nṣe, ngbọ ki iṣe ẹjọ rẹ ṣa, ẹjọ Iyawo rẹ ni, ẹjọ awigbọ, akọgbọ, ti o ntode kọ ọgbọn wale ni.

LATI ỌWỌ

Afolabi Olabimtan

Ohun ti emi ni sọ ṣa ni pe, ki o wa ọ n a kọna lati da Iyawo rẹ ni oko owo, ki o si ṣi ile Itaja kan fun. Oluwa ti da nyin pọ, ko si ni ya nyin Amin. Bayi ni Ana Ojogẹ ṣe ba a sọrọ, o si ba tirẹ lọ.

Nitotọ Iyawo Ojogẹ kọ delẹ ko lọ gba Ọja mọ, Iwa rẹ si nburu si ninu ile, ko t u n bikita mọ fun Ojogẹ, Ọkọ rẹ si di ẹni amọri iba ku, ọpọlọpọ igba ni Ojogẹ pe Iyawo rẹ ti o nbẹ pe ki o yi iwa pada, ki o ranti bi awọn ṣe fẹ ara awọn ati pe ti o ba le ma ta ọja rẹ bi ti atẹhin wa, laipẹ owo diẹ ni on yio fi kun ti awọn yio si ṣi ile Itaja nla.

Nigbati Ojogẹ ba sọrọ yi, ọkan aya rẹ a yi, ṣugbọn nigbati Iya ba de, a tun ki lọkan pe, ko gbọdọ yipada O si sọ fun pe "Nisisiyi Baba rẹ ti kọ ẹhin si ọ, ẹṣẹ ti o ba tun gbe ninu ọrọ ti o wa nilẹ yi, ni ngo fi mọ ohun ti emi na yio ṣe.

Ọkan muli a tun daru, laisiyemeji o fẹran Ojogẹ, ṣugbọn ko tun fẹ ṣẹ Iya rẹ, Iya papa si ti fihan ni ọpọlọpọ igba pe on fẹran O j o g ẹ, ṣugbọn on ko fẹ ki Muli ma wọ kiri. Njẹ ki o f u n Muli lowo, o ni on ko jẹ fun nitori Baba rẹ yio binu si, I y a Muli yọ gbongbo si ifẹ to j i n n a, o yọ igi si ifẹ atata, Ana Ojogẹ yọ ọpa nla, ile Ojogẹ, Iya Muli wọle, o nda ile ru, Ana nla de, Ọkọ ko gbọ isọ Aya, Alafia bẹrẹ si sa diẹdiẹ kuro nile Ọkọ Muli, Inu Aya ko dun bẹni ọkan t'Ọkọ ko duro Ifẹ wọn jinlẹ pupọ, gbogbo igba na si ti nṣe fikofiko to, ko dinku lọkan Ọkọ tabi Aya rara ṣugbọn M u l i ko fẹ lati ṣe Iya rẹ mọ nitorina o kọ lati gbọ ọrọ si i lẹnu, Ojogẹ ko si ni owo lọwọ to bẹ ti yio fun Muli, nitorina ko si alafia larin wọn.

AKIYESI:— Tani nsọ ọmọ doloriburuku? Kini Ojogẹ wi fun Akin? Iru esi wo ni ọrẹ rẹ fun? Njẹ Ojogẹ ṣi ile-Itaja na f u n Iyawo rẹ bi? Ki o to le dahun Ibere yi, ayafi ki o ka Irohin Imọlẹ ọsẹ to mbọ.

---

## Akiyesi

Enikẹni ti o ba fẹ ra iwe IROHIN-IMOLẸ fun kika tabi o nfẹ polowo Ọja sinu rẹ tabi o ni ọrọ lati sọ nibikibi ni agbegbe Dahomi, Weme, Gerefe, Ajasẹ Abomi-Kalafi Mahin tabi Mẹkọ, k o lọ si ọdọ:—
MONSIOR L. M. ADESIYAN ILE IFIYE, ONIFAJI
PORTONOVO DAHOMEY

# Igbomina kole fi mogbọn-tan gba Division

ILORIN:— Ọkan ninu awọn Oniwe Irohin wa kan lo rin irin ajo lọ si Ilorin, tibẹ lo si ti gbọ awọn ọrọ wonyi:—

Ọpọ awọn enia sọ pe nitori ti awọn Igbomina ma ba tun pada sinu ẹgbẹ Ọlọpe ni ko jẹki ẹgbẹ N. P. C. gba lati fun wọn ni Divison, bọkọ rara, ọrọ ko ti bawọnni

Idi rẹ niyi, Kọ nṣe Igbomina, nikan ni yio kọkọ gba Division lábẹ Ilorin. Kabba ti gba Division, Pateji gba, Kiyanmọ gba, Lafiaji gba, ṣugbọn awọn Igbomina fẹ fihan wipe awọn laju ju ti Ilorin lọ.

Kaka ki awọn mu lọna ti ẹrọ awọn fẹ mu lọna ele. Pẹlu pẹlu awọn ara Ilorin ko ho o. Nitorina ẹniti o ba wa wipe kini, o o ṣe, on ni ni o ṣe ban.

---

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:—

RICHALET FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO




Eleyi yato patapata si awọn Egbogi ... Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Monomọno.

Mẹji rẹ kọsi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri, ni owo pọọku, adimọwo tabi ki o lọ nile ko di owo. Iyẹn se e w ọ nwa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npota ni Ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ iriṣẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ba ojulowo egbogi atata ti araṣẹ fun titi lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti a w ọ n Tatambulu si Itali jẹ mọ daju pe bi ejẹ ara kọ ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọn yi le ṣe o Ikkitogbe, orisirisi Inarun, Ojuṣuṣu tabi didun, Jẹdi-Jẹdi, Ako-Iba, arun Edọki, Aya didun, Tanpara ati Esuru laya ara riro, Lapalapa Egbo ẹsẹ Amodi Apọ ile ato, ẹlun didun tabi Ibaradi rro p ọ l u egbogi Risaleti a ma pa gbogbo kokoro buruku ti o wa n i n u Eje ara patapata yio si fo ejẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu. Si dsn Igo rẹ kan wo lara rẹ daradaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran p ẹ l u nigbakugba.

Bere ni Sọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.
Phone: 22878 (Oja ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 2287

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

ATI NI SỌBU IBADAN:-
ISẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA

# Ẹ ma ṣe Inurere ẹnyin ọmọde ki ẹ si ma sọ otitọ

LATI OWO:- KOLAWOLE IDOSU
No. 191 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Nigbakanri ọkunrin Akuṣẹ kan wa ti o bi ọmọ mẹta Orukọ ekini a ma jẹ Tinubọri, ẹkeji a ma jẹ Bojuri ati ẹkẹta Ọdẹ. Ọkunrin yi kuṣẹ ti ko fi ri owo tọju awọn ọmọ wọnyi, ọkunrin yi si ni Iyawo kan ti orukọ rẹ njẹ Onisẹgin. Nigbati ọdọ ọjọ kan baba awọn ọmọ wọnyi pe wọn o si sọ fun wọn pe on fẹ ki nwọn ma se owo igi tita ki olukaluku wọn ma tọju owo tirẹ lọtọtọ. O si tun wi fun wọn pẹlu pe on nfẹ ki eyiti o dagba ju kọkọ lọ si Igbo igi kio lọ sẹ igi tirẹ, lẹhinna ki eyiti o tun tẹle tun lọ ati ẹkẹta ti orukọ rẹ njẹ Ọdẹ.

Ohun ti o mu ti wọn fi npe eleyi ni Ọdẹ ni pe o fẹran lati ma ṣe iṣẹ, ko si ki nba ẹnikẹni ja ṣugbọn awọn ẹgbọn rẹ mejeji wọnyi jẹ ọmọ buruku patapata wọn si fẹran lati ma bu ẹnikẹni ti wọn ba ri tabi ki wọn ma fi ṣe yẹyẹ. Ki a ma fa ọrọ gun lọ titi eyiti o dagba ju mura lati lọ si Igbo lọ ge igi fun tita.

Nigbati o si ma lọ, Iya wọn fun ni ẹlu waini ati buredi o si mura o lọ.

Nigbati o de ọhun o ri Ọkunrin arugbo kujẹkujẹ kan Ọkunrin na ki o si da lohun, lẹhinna ọkunrin na si tun bẹ ẹ ki o fun on ni onjẹ diẹ jẹ ninu onjẹ rẹ, ṣugbọn ọmọ na sọ fun pe on ko gbe onjẹ wa ati pe Igi lasan, ni on wa ge. Inu bi ọkunrin yi pupọ nitori o ti ri onjẹ ninu apo ọmọ na ṣugbọn o si dakẹ o si ba tirẹ lọ. Bi o ti lọ tan ni ọmọ yi bẹrẹsi nge Igi nigbati o si rẹ ẹ o joko si abẹ Igi nla kan lẹba ọdọ rẹ o simi.

Bi o si ti simi tan ni o bẹrẹ si njẹ onjẹ rẹ, Ibiti o si ti njẹun na lọwọ ni Ọkunrin yi yọ si i. Ẹru ba ṣuba o si ṣe bi ẹni pe on ko ri, lẹhinna Ọkunrin yi tun lọ bẹ pe ki o fun on ni onjẹ diẹ, Ọmọde na ko gbọ

Nigbati Ọkunrin yi ri bayi o binu o si ṣepe fun ọmọ na o si ba tirẹ lọ.

Ko pẹ pupọ ti ọmọ yi jẹun tan o si tun bẹrẹsi ge igi rẹ lọ. ṣugbọn ọwọ ti o gbe soke pe ki on ṣa igi na o si baa ni ẹsẹ, o sa ni ẹsẹ wọle, ọmọ yi sare pada lọ sile. Nigati o de ile, ẹru ba baba ati iya wọn, nwọn si paṣẹ ki ẹnikẹni ma se lọ sinu igbo na mọ.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA

# Yẹs kẹ, Ẹ bẹrẹ Ẹfẹ



Omode binrin ti a nwo ninu aworan yi ... Omode orin asiko lehin ti o ti luwẹ tan ninu odo, Ẹrọ ti o nkorin na lo fi ha ṣokoto rẹ, o wa g'e igboro rẹ si eti o si ngbadun orin asiko "Yẹs kẹ, ẹ bẹrẹ ẹfẹ."



# Olori Omuwe Omoge Ile Gesi



Omobinrin ti a nwo ninu aworan yi ni Omidan Anti Long tise omo ile Gesi ti o lo se ere Ije Olympic ti won nse nilu Rome lodun tokoja. Omidan Long nyo ara wo fun aso ti awon elegbe re wo fun ti ere Ije Olympic Omidan yi lo je Olori awon Omuwe olilu Gesi, odun kowa re ti o tun je Olori awon ti o ba wo inu omi, o mo luwe ti o fi je pe ti o ba ko sodo o le ri to ibuso meta ko to yo ori soke, Irohin ko to afojuba ni ti Omidan Long nipa iluwe ninu odo. Ninu ere Ije Olympic na ti nwon se lodun tokoja omo Naijiria ekankan. Nitorina a fi iwe yi pe gbogbo enyin omo ile Naijiria ti o je omo egbe elere Idaraya ki awon mura lati le je ki awa na ni iru fe obinrin ti yio gba irufe ipo Omidan Long yi nile wa.

O BERE LATI OJU-EWE KARUN

Lehin ojo melo kan, eyi Abigbehin ti oruko re nje Ode pinu lati lo o si lo ba b a b a re lati toro aye lowo re sugbon baba re koo fun, o bee titi, nikehin o fun l'aye lati lo o si lo ba iya won lati gba ounje lowo re.

Iya won feran omo yi pupo ko si fe ki o lo l'srapa bi ti egbon re. Sugbon omo na pinu lati lo, Iya won si fun ni oti Waini (wine) ati Buredi (bread) bi ti egbon re bayi ni omo yi mura ti o lo. Nigbati omo yi de ibe o ri okunrin arugbo kan na yi, okunrin yi si be pe kio fun on ni ounje je ninu onje re. Omode yi so f u n pe onje die ni on mu wa, on ko si ni ero wipe yio to awon. Sugbon bi o ti je wipe kole nkan ni so ni d'ahun, on yio gbe sile awon yio si jijo je. Loto omo yi gbe ounje yi sile on pelu okunrin arugbo na si jijo je.

Nigbati won jeun tan okunrin Arugbo na so fun omo na pe on rope ko ni fun on je ninu onje re bi ti egbon re, sugbon nitori pe o fun on je; on yio fun ni ebun kan ti iwo pelu awon obi re yio fi di Olowo. Lehinna o na owo si idi igi kan fun omo yi, o ni ki o ge i g i na lule, yio si ba ohun Alumoni kan l'abe re kio gbe lo sile won. Nigbati o wi bayi tan o gba ona ire omo yi pepa si mura o di idi igi yi, nigbati o debe o beresi nge igi yi titi o fi ge lule, o si ba Golu ,eiye Golu apo owo meta ati apoti aso olowo-iye-biye nlala meji pelu. Inu omode yi dun rekoja ti ko fi mo ohun ti iba se, nikehin sa o ko gbogbo re lo sile.

Nigbati awon obi omode yi ri gbogbo ohun ti o ko wole yi inu won dun, won si bere bi omode yi ti se ri gbogbo dukia wonyi o si se alaiye gbogbo r e fun won. Awon Obi omo yi ta gbogbo eru wonyi, won si di olowo to fi je wipe okiki won kan jakejado gbogbo Ilu won. Nigbati omode yi si ma fe Iyawo omo-oba ni o fe, lehin ti oba ku tan omode yi ni won fi je oba Ilu won. Nje enyin omode e ko ri bi inurere ati otito se so omode abigbehin yi di olowo ati oba nitorina e je ki a fi eleyi se arikogbon ki awa na si ma so otito, ati ki a ma hu iwa rere lati oni lo.

BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI

"UROXAL"



Fun Itoju tabi fifo Ape Ile Ito Kidney-Bladder fun Okunrin ati Obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu Ehin didun eri ile ito tabi ito-jijo enia, ito rirun, rukuruku Pipon rirun, lakuregbe, ibaradi wiwo, orunkun, owo, ese, Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara konkon tabi kiakia didaji loru nigbakugba, ati orisirisi awon aisan tabi amodi ba wonyi ni egbogi aje bidan yi yio wo san lara re ni kia kia ti alafia yio si de si o. Meji re kosi ni ilu Naijiria nitorina sora ki awon eleru tabi awon Obi robirobi ma ta orisi omiran ti ko ni lati fun e, mase gba a rara o!
Owo re je Sile Mejo abo 8/6d
owo Oko Sile meji abo (2/6d)
Bere Egbogi yi ni sobu awon Saro ti won npe ni:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA

# ENAHORO SỌ IDI IJA OLOYE AWOLỌWỌ ATI AKINTỌLA

Oloye Tony Ennahoro, baba isalẹ ẹgbẹ A. G. jakejado aiye sọ idi Ija ti o bẹ silẹ ninu ẹgbẹ. O ni lati igbati rogbodiyan ti bẹ silẹ ni ọpọlọpọ enia lorișirişi ti nranşẹ si on lati mọ idi ija, ati lati mọ dajudaju bi awọn Alagba inu ẹgbẹ ba nșe eto totọ lati pari Ija na.

O ni "ni idi eyi, o jẹ mi logun lati sọrọ diẹ nipa rogbodiyan ti o nlọ ninu ẹgbẹ wa." O ni ti enia ba fi oju balẹ ti o ri ohun ti o fa rogbodiyan yi yio mọ pe bi ko ba şẹlẹ ni akoko yi, o pẹ ni o ya ni yio şẹlẹ dandan.

Enahoro ni ni iwọn igbati A. G ti wa ni Alatako ni Eko ti o si tun nşe Ijọba ni Ibadan ni ijaiya ti wa pe g u d u gbẹ yio bẹ ni ọjọ kan larin ẹgbẹ. Şugbọn iru gudugbẹ yi şe şe ki o ma bẹ ti Igbakeji Olori ẹgbẹ ti o nşe olori Ijọba ni Ibadan ba nfọwọ wẹwọ pẹlu olori gbogbo ẹgbẹ ti nşẹ olori alatako ni Eko. O ni şugbọn ko si eyi larin Oloye Awolọwọ olori ẹgbẹ ati ọloye Akintọla Igbakeji rẹ.

O ni orişirişi işẹlẹ lo ti şẹlẹ pupọ eyiti ko yẹ ki on sọ sita nisisiyi ti o fihan gbangba pe nwọn fẹ gbe oye olori kuro lori Awolọwọ ni. O ni şugbọn bi gbogbo enia iba şe riran to ninu ọrọ yi awọn onidaru ko jẹ.

Lẹhin gbogbo eyi, Iwa awọn Olori ti nja tun ni işe pẹlu rogbodiyan na. O ni Awolọwọ ko mọ ayinike, enikẹni ni o si le mọ ibiti o ba tẹ si. Akintọla mọ ayinike o si şoro ki enia to le mọ ibiti o tẹ si ti ọrọ ba delẹ.

Oloye Enahoro ni ju gbogbo rẹ lọ awọn ibere ti o şe pataki ti Ẹgbẹ ni lati dahun ki ija na to pari patapata ni iwọnyi:-

EKINI: Şe ijọba ti ẹgbẹ yan ni o yẹ kio ga le ẹgbẹ lori ni tabi ẹgbẹ ni o yẹ ki o ma şe amona fun Ijọba lati şe ohun ti egbẹ ba fẹ? Şe egbẹ ni o ni lati ma şe ohun ti Ijọba ti o yan ba fẹ ni tabi Ijọba ni o ni lati şe ohun ti ẹgbẹ ba fẹ?

Larin ọdun mẹwa nigbati ẹgbẹ şẹşẹ daiye, a ko ni idi lati bere eyi nitoripe enikan'şo ti o nse olori ẹ g b ẹ na ni olori Ijọba, Şugbọn idi miran ti o tun n i p ọ n nipe olori Ijoba nfi ọrọ lọ ẹgbẹ nigbagbogbo ki o to şe ohunkohun, ohun ti o nşẹlẹ nisisiyi nipe Oloye Akintọla ro pe ẹgbẹ ni lati ma gba fun kio si ma şe ohunkohun ti Ijọba ọn ba fẹ biotilẹjẹpe ẹgbẹ ni o yan sibẹ gẹgẹ bi Aşoju Ẹgbẹ ninu ilu şişe.

Ibere keji nipe, "Şe Iwọ-Orun nikan ni ki A. G. ti ni ọmọ ẹgbẹ, şe ki ẹgbẹ kọ ẹhin si awọn ọmọ ẹgbẹ tio wa ni Ipinlẹ yoku?" Enikẹni ti o ba sọ hẹn si eyi ko ni arojinlẹ rara. Ọkan ninu alebu ti yio si mu wa ni pe awọn Yoruba nikan ni yio ma şe ẹgbẹ igbẹhin eyi yio si buru gidigidi.

ẸKẸTA 'Nje o yẹ ki ẹgbẹ A G. tẹle e t o wọn pe ki tọmọde tagba ati olowo ati talaka n i j ọ ni igbadun?' Bi o tilẹjẹpe gbogbo ẹgbẹ fi ohun si eto yi ni 1960, ti Oloye Akintọla ko si lodi si ohun ti o nsọ nipa rẹ nisiyi o fihan pe o ti bere si lodi si i. O ni itumọ eto yi ni pe bi enia ba ni şokoto ko gbọdọ ni buba, bi enia ba si ni ju iyara kan Ijọba yio pe lẹjọ, bi enia ba si ni basikulu ko gbọdọ lọkan ati ra mọto. Iru itumọ ti Oloye Akintọla nfun eto ti yio şe gbogbo ilu pa-a-pa mọ kunnu lore ko jẹ ki awọn ọ d ọ ati gbogbo eniti nfẹ ilọsiwaju fi tọkan-tọkan tẹle ọrọ rẹ mọ.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸJỌ


## PAYAL (IPARA)

Ati awọn orisirişi omiran ti irufẹ rẹ jẹ ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu ni ode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba Alefọ. Egbo Ẹsẹ orişirişi tabi ti ojo rẹ ti pẹ bi Adajinọ Egbo, Ekuşẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisan, Akọ Inarun, Sobiya Afọju ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi kokoro titun ti awọn ara Ilu Tatambulu şe iti wọn npe ni "PAYAL" wo larin ọjọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu.

Egbogi ipara yi ki şe awọn tọbirọbi ti w ọ n n t a kakiri Ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si şişẹ iyemeji ninu rẹ eleyi si ya tọ patapata si awọn egẹrọmiti adiwọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu. Orişi meji rẹ lowa. Kekere ati Nla.

Bere Egbogi Ajẹbina PAYAL yi ni Şọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 2287

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OŞHOGBO.

ATI NI ŞỌBU IBADAN:-
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY UKE BỌLA


# Awọn Oselu ilẹ Naijiria lọ bẹ ilẹ Gẹsi wo



Aworan enia mẹta ninu awọn Oselu Naijiria ti wọn lọ şe abẹwo ilu Gesi, ni awọn mẹta ti nwọn duro ni iwaju Balliol C o l l e g e, oruko wọn ni wọnyi:- Oloye Ọlọla E. A. Anuku. Oloye Gogo Abbey ati Alhaji Ahman Galidiman Pategi.

